# ÀDÚRÀ LÁTI DÁ WỌN DÚRÓ KÍ WỌN TÓ DÁ Ọ DÚRÓ (APÁ KEJI)

**Bíbélì Kíkà: Ẹsteri 7/Ìjẹ́wọ́: Deut. 33:27**

1. Agbára òkùnkùn ti wọn yan lati fi mi ṣòfò, Olúwa, kede isinku wọn, ní Orúkọ Jesu.
2. Aṣọ ikú ojiji ti wọn ran fun mi, pada ki o lọ ṣeku pa àwọn ti wọn ran ẹ, ní Orúkọ Jesu.
3. Ijamba yoo wu ti wọn ran niṣẹ lati mu ki àwọn eniyan ba mi sọkun, pada sọdọ ẹni to ran ẹ, ní Orúkọ Jesu.
4. Àwọn eniyan ìkà yoo wu, to npese posi ikú aitọjọ fun mi, wọnu posi na, ki a si gbe ẹ sin, ní Orúkọ Jesu.
5. Ọfà ikú aitọjọ ti wọ ta soju ala mi, pada si ibi to ti wa, ní Orúkọ Jesu.
6. Gbogbo ilẹkun ti o ṣi fun idojukọ iku aitọjọ ninu aye mi, tii nipa ẹjẹ Jesu, ní Orúkọ Jesu.
7. Iranṣẹ iku, ti wọn yan lodi si mi, mo fọ yin loju, mo si ran ẹ pada sọdọ ẹniti o ran ẹ, ní Orúkọ Jesu.
8. Ikú aitọ́jọ́, kọlu gbogbo aṣoju òkùnkùn to nwa ẹmi mi, ní Orúkọ Jesu.
9. Gbogbo agbára ibi , ti wọn ti yan ọjọ́ iparun mi, ẹ ṣubu lulẹ ki ẹ ku lataari ohun ibi ti ẹ yan, ní Orúkọ Jesu.
10. Ki a ge orí Hammani mi pẹlu idà kanna ti wọn fẹlo lòdi si mi, ní Orúkọ Jesu.
11. Oluwa jẹ ki àwọn ọ̀tá mi ṣubu sinu kòtò iparun ti wọn wa silẹ fun mi, ní Orúkọ Jesu.
12. Agbára to korira ati ri mi laaye, mo gbe ọ sin loni, ní Orúkọ Jesu.
13. Gbogbo aṣe pari iṣẹ́ ọ̀tá lori aye mi lati ke ẹ̀mí mi kuuru, yi pada ki o si ke ẹ̀mí wọn kuru, ní Orúkọ Jesu.
14. Gbogbo ọ̀tá ti o dibọn bi ọ̀rẹ́ ninu aye mi, ti o si pinnu lati gbẹmi mi yoo di ẹni ana, ní Orúkọ Jesu.
15. Gbogbo ẹnu to nkede ikú lori aye mi, ẹkú rọpo mi, ní Orúkọ Jesu.
16. Oluwa jẹki Angẹli Iná Rẹ, rọgba yi èmi ati gbogbo mọlẹbi mi ka, ní Orúkọ Jesu.
17. Mo paṣẹ pe labẹ akoso bi o ti wun ki o ri, emi ki yoo ku saaju àkokò mi, ní Orúkọ Jesu.
18. Oluwa baptisi mi pẹlu ẹmi gigun ati iṣe rere, ní Orúkọ Jesu.
19. Ẹjẹ̀ Jesu, mọ odi abo Rẹ yi mi ka, ní Orúkọ Jesu.
20. Mo sọọ pada, òkuta ikú ti wọn sọ sinu ayé mi, ní Orúkọ Jesu.
21. Emi yoo rẹrin kẹhin lori àwọn ọ̀tá mi, awọn ọ̀tá mi ki yoo yọ mi, ní Orúkọ Jesu.